# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV 856 LAGOS SATURDAY FERUARY 9th — FEBRU RY 15th 1963 KỌBỌ MEJI (2D)

Gongo So L'Ehingbeti !

# Awon Osise Oko Da Ise Sile; Ijakadi Besile Larin Olopa Ati Awon Osise

## Nwon Wa Awon Lebira Lo Si Ilorin

EKO—Awọn ọga alagbaṣe iṣẹ ti nwọn ngba awọn lebira siṣẹ a-n-ko-ẹru lebute ọkọ elefin ni Apapa ti tuka si igberiko Ilorin lati ma wa awọn lebira ti yio ṣe iṣẹ fun wọn l'Eko kakiri nitori awọn ogunlọgọ awọn kan ti nwọn ti da iṣẹ silẹ ni ebute ọkọ elefin ni Eko, Apapa, Warri, Sapẹlẹ ati Port-Harcourt nitoripe owo iṣẹ ti nwọn nfun wọn ko to awọn lo.

Awọn oṣiṣẹ na ti wa lẹnu nwọn ba awọn ọga ti o gba wọn siṣẹ yi fa ọrọ a-nfẹ-owo-si yi ti pẹ ṣugbọn gbogbo rẹ ko lori ko nidi ki o to di ijẹjọ ọjọ Satide ni gbogbo awọn oṣiṣẹ na, awọn bi ẹgbajọ enia ba binu da iṣẹ silẹ bamu-bamu, nwọn ni a fi bi awọn onisẹ na ba bu owo si owo iṣẹ awọn; nwọn ni ṣilemejila ati abọ ni awọn nfẹ dipo ṣile mẹfa ojumọ ti nwọn nsan fun awọn.

Nwọn fi ọrọ logun nwọn fi lọgbọn awọn oṣiṣẹ yi faake kọri wipe a fi ti awọn ọga onisẹ yi ba f'owo kun owo awọn.

(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)

## Awon Olote Tun Lu Alakoso Ilu Kan Pa Lana

BAGDAD— Awọn ọlọtẹ ilu ti nwọn npe ni Iraq ti pa alakoso ilu wọn ti orukọ rẹ njẹ General Kassim ni oru alẹ ana eleyi jẹ irohin pataki kan ti a gbọ lọdọ awọn Onirohin gbogbo agbaiye lọdọ awọn onirohin gbogbo agbaiye lati Bagdad.

Orukọ awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu Ọlọtẹ ti nwọn lu alakoso ilu wọn na pa njẹ NATIONAL COUNCIL for Reuolutionary Command.

Nwọn ni awọn ri wide ijọba alakoso na ko dun mọ gbogbo awọn ara ilu ninu lara rara.

A gbọ wipe nwọn ti nlepa lati pa alakoso yi ti pẹ ti ko bọ si. Akọkọ ni ti ọdun kẹrin sehin.

## Oro Enkuari Di Koko:

## Awon Soja Ilu Togo Fake Kori Pe Awon Ko Fe Enkuari Ni Ilu Awon Mo

LOME— Ọrọ ẹnkuari (iwadi) lori iku Olympio ti onirohin wa kan tẹ waya lati Cotonou (Dahomey) ni ọsẹ ti o kọja si wa wipe nwọn ti npalẹmọ lati gba awọn ikọ orilẹ-ede ilu Afrika marun ti awọn ogunna-gbogbo yan ninu ipade nla l'Eko wipe ki nwọn ṣe iwadi iku ti o pa alakoso ilu na lọwọ awọn ọlọtẹ, ni awọn ko fẹ ki alejo kan wa da si ọrọ ilu awọn nibi nitoripe awọn ni awọn mọ idi gbogbo nkan ti o bẹ silẹ nilu awọn ki awọn to fi agbara gba ijọba lọwọ alakoso Ijọba ilu Togo.

Gbogbo awọn aṣoju orilẹ-ede mẹta ninu awọn marun ti apejọ awọn ogunna gbogbo yan ni ipade nla ti nwọn ṣe l'Eko ti nwọn si ti de si Lomẹ ni awọn ṣoja jagunjagun ti wipe ki nwọn pada si ilu wọn, AYE-KO-ṢO rara lọdọ awọn.

(Wo iyoku ni oju ewe keji)

# Ka Irohin . . .

Sardauna Ti o lo si Oju Orori ni Meka ni oju ewe Keji (2)

Ilu Togo " " Keta (3)

Jesu Oyingbo " Karun (5)

Owo awon Lebira oju ewe Karun (5)

## Akowe Ilorin Pa Iyawo Soju Titi

ILỌRIN— Agbako ori ede! akọwe Ijọba kan ti o nṣiṣẹ nile ibili awọn Ijọba ti ngba enia ṣiṣẹ ni a gbọ wipe o ṣa iyawo rẹ ti o ntọ ọmọ lọwọ pa lọsan gangan ni arin ilu Ilọrin lori ọrọ ti ko to nkan.

Ọrukọ akọwe na njẹ Chukuma Ogbanisiegbe, ẹni ọdun mẹtadinlọgbọn; iyawo alara paapa njẹ Justina iṣẹ tiṣa ni o nṣe, osi ntọ ọmọ ọdun kan lọwọ ki ọkọ rẹ to pa a.

Irohin ti a gbọ nipa ija wọn na ni wipe iyawo yi ton pẹlu ọkọ rẹ ni ija awọ kekere kan larin ara wọn, obinrin na si sa kuro nile, o lọ si tesan ni ọdọ awọn ọlọpa lati lọ fi ẹjọ ọkọ rẹ na sun wipe ki nwọn pari ija na fun wọn.

(Wo iyoku loju ewe keji)

# Akowe Ilorin Pa Iyawo Re Soju Titi

( O berc loju ewe kinni )

Ẹru ko m nkan ti ọkọ rẹ na 'e sɛ fun un ko jẹ ki o sun ninu ile ni alẹ ọjọ na, sugbọn nigbati ilẹ mọ o gbe ọmọ ti o ntọ lọwọ lati lọ jiṣẹ awọn ọlọpa fun ọkọ rẹ.

Bi o ti de ibẹ ti o kan ilẹkun igudan ni ọkọ rẹ fayọ si pẹlu ọmọ ti o pọn si ẹhin, ni iyawo yi ba sare bọ si ita ti o nkigbe "ẹ gba mi ! ẹ gba mi !!

Ọkọ yi sare tẹle lẹhin titi ti obinrin na fi subu lulẹ o sa a pa nibi to gbe ṣubu si.

Awọn ara adugbo ni ọrọ na ko ṣe oju lasan; nwọn ni boya tira awọn Alufa ni awọn ti nwọn nwa iṣẹ lọdọ rẹ sa si i.

Ju gbogbo re lọ ọwọ awọn ọlọpa Ilorin ti tẹ ẹ nwọn si mba ro ẹjọ apania lọwọ nisisiyi.

A ri waya gba wipe oju ọna bode ti awọn ero ngba lati ilu Togo, Nigeria ati Dahomey lọ si Ghana ti nwọn ti fi igba kan ti lati igbati nwọn ti pa Dokita Olympio ni a gbọ wipe nwọn ti si nisisiyi nwọn si ti fun awọn ero laye lati ma kọja si Accra ṣugbọn ọpọlọpọ awọn ṣoja ni nwọn si nṣọ ibẹ. Ṣaju eyi ọpọlọpọ nkan owo ni awọn oniṣowo ilẹ Nigeria ti pa ladanu, nkan bi nkan onjẹ, bi elubọ, gari, alubọsa, ẹyin-awo ati malu ni nwọn bajẹ patapata ni Afloa.

# Oro Enkuari Ni Ilu Togo

( O bere lati oju ewe kinni )

Irohin ti a gbọ lọdọ Ọgbẹni M T Mbu Minisita alamojuto eto awọn ọmọ-ogunoju omi ti Ijọba Nigeria ran lọ gẹgẹbi aṣoju wa, nigbati o gunlẹ si Ikẹja o ni "ọrọ ko pariwo, nkanti a ba lọ ko ti bọsi rara, mo ni lati pada ṣugbọnko ti si ẹnikan ti o le sọ ni gbawo ni.?

Onirohin wa lati Cotonou ni gbogbo asiko ti awọn ikọ ti awọn achaiye orilẹ-ede ilu Afrika yan ṣe nilu Lomẹ ni Togo pẹlu ibẹru ibojo ni, nitoripe ọga awọn ṣọja ibẹ ni nkankinkan ti o ba ṣe wọn ki nwọn mọwipe ko si ọwọ awọn nibẹ.

Tẹlẹtẹlẹ ki awọn ikọ yi to wa si Lomẹ nwọn kọ fi igba kan pejọ si Cotonon (Dahomey) lọdọ alakoso Ijọba ilu na ti nwọn npe ni Hubert Maga lati jiroro nkan ti awọn yio ṣe nipa ọrọ iwadi (ẹnkuari) ti awọn fẹ lọ ṣe iwadi ni Togo.

### Bode Ghana

Ni Ijeje, Ọgbẹni Nicholas Grunitzy, alakoso tuntun ti awọn Ọlọtẹ fi rọpo Dokita Olympio ti nwọn pa, lọ si ọdọ Hubert Maga, alakoso Ijọba ilu Dahomey lati lọ dupẹ lọwọ rẹ fun gbogbo wahala rẹ ti o ti nṣe lori ilu awọn nigbati rogbodiyan na ti bẹ silẹ. On pẹlu Ọgbẹni Antoine Meatchi tiṣe minisiter alamojuto eto inawo Ijọba tuntun ilu Togo na ni nwọn jọ lọ ki Maga na.

# Sadauna Lo Se Adura Loju Orori Anabi Ni Ilu Meka

MECCA—(Saudi—Arabia)— A ri waya kan gba ni oru ọganjọ ana wipe alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa (l'Oke Ọya) Ọlọla Alhaji Amadu Bello, Sardauna Sokoto pẹlu awọn ẹmẹwa kan ti o mu lọwọ ti gunlẹ si ebute Jẹdda ni ana, gbogbo wọn si ti re kọja si apa keji lati ma lọ si ilu Mẹka.

Akọwe onirohin ti o fi irohin na ṣọwọ si wa ni ọkọ ẹropileni odidi nla kan ni Ọlọla Amadu Bello na gba ti o fi ko awọn lọba lọba ilu rẹ pẹlu awọn enia oṣelu jankan-jankan, awọn bi alaga ile Igbimọ aṣofin Ipinlẹ ariwa na ati Alhaji Sa'du Alanamu, tiṣe Aṣojn Ijọba Ipinlẹ ni ilu Oyinbo, gbogbo awọn enia ti o tẹle Sardauna na lẹhin jẹ enia marunlelọgọta.

Nkan ti o jẹ pataki ti a tun gbọ nipa irin ajo abami na ni wipe nwọn wa ṣe "KUNKARI" kan pataki ni ilu Mẹka ni.

Irohin ti a gbọ lati Kaduna ki Ọlọla Sardauna to kuro nile ni wipe o fẹ lọ si oju orori Anọbi nibiti nwọn gbe sin in si lati lọ gba'wẹ, ki o si ṣe adura fun ọjọ meje gbako ki o to pada wa sile ni ọjọ mẹfa loni.

A gbọ wipe iru awọn enia ti o nlọ ṣe "kunkari" bayi ni ilu Mẹka nigba awẹ ko wọpọ, o si ni lati jẹ wipe oluwarẹ nlepa nkankan lọkan rẹ ti o fẹ gbadura na fun.

Sardauna, adura yio gba o, ki o maṣe gbagbe ilu Nigeria ninu adura "KUNKARI" na o.

# Gomina — Agba

**Aworan otun yi ni ti Ololа Dokita Nnamidi Azikiwe, Gomina-agba fun Ijoba Apapose ile Nigeria nigbati o mba enikan soro ninu awon oselu wa ni oke Oya. Gomina-agba na sese ti ibiti o gba losinmi ni ilu Nsukka de ni ninu ose yi, o si tun fi ese kan duro ki awon ara Oke Oya ni Kaduna.**



# Bawo Ni Olympio Se Ku Lori Oro Ilu Togo..? (3)

## MILITIA

Eyi ni yio di iwe keta ti emi Olofintoto yio kọ ni akọle lori ọrọ bawo ni ilu Togo ti ri nipa awọn oṣelu rẹ lati bi ọdun kẹrin tabi ikarun sẹhin. Mo si ro wipe enyin ọkawe mi paapa si ti nmọ itan awọn alamulegbe wa na nisisiyi, nitoripe ko ba oju mu rara, ki o jẹ wipe awọn Oyinbo ajoji ni yio ma sọ itan ilu wa fun wa ki awa na mọ ti'e mọ diẹ nibẹ. Awọn Oyinbo Jamani (Germany) ni nwọn njọba lori awọn ilu Togo yi ni iwọn nkan bi ọdun mọkandiladọta. O di ọdun marunlelogoji nisisiyi ti Ogun ajakaiye kinni pari ti awọn Ijọba agbaiye (League of Nations) da ilu na si meji, ti nwọn ko apa kan fun awọn Oyinbo Gẹsi, apa keji fun awọn Faranse: ibiti nwọn pin fun awọn Faranse ni ilu ti nwọn ti fi ọtẹ pa Dokita Olympio ti mo nṣe ofintoto rẹ fun enyin ọkawe mi yi.

## LATI OWO OLOFIN TOTO

Alaye ti mo tun ṣe fun yin yi a jẹki o le ma fi ọkan gbe iwadi mi na lọ daradara. Mo ni ede kan ti nwọn npe ni EWE ni awọn ara Togo nfọ, nwọn ko si jinna pupọ si ilu Ghana — awọn ni o ba Ghana p'ala pọ. Awọn Aganyin Ghana tilẹ nsọ wipe ọkanna ni awọn pẹlu ara ilu Togo yi.

Awọn Oyinbo mejeji (German ati France) ti awọn ara ilu nwọnyi ti nṣin, alagbara ni wọn nwọn si fẹran nkan jagunjagun pupọ nitorina ofin ni labẹ ijọba Faranse pe gbogbo awọn ọdọmọkunkunrin ni lati kọ iṣẹ jagunjagun mọ ẹkọ ti nwọn ba nkọ nile'we. O fẹ, o kọ, o ni lati lọ ba awọn ẹgbẹ rẹ se iṣẹ MILITIA.

## Owo Ko Si

Iṣẹ MILITIA (iṣẹ jagunjagun) yi ni o jẹ ogun patakiti awọn Oyinbo Faranse fi silẹ fun awọn ara ilu Togo na nigbati nwọn fẹ fun wọn ni Ominira ni iwọn ọdun mẹta sẹhin. Eleyi ko jẹki awọn ara ilu na mọ iṣẹ owo lati ṣe tabi ki nwọn ronu ọna ti nwọn le gba ti nkan aje le ma fi wọ ilu wọn, ti nwọn yio mọ ri owo na fun nkan ilọsiwaju ilu na.

Eleyi lo jẹki gbogbo rẹ le fun Ologbe Dokita Olympio nigbati o gun ori aga gẹgẹbi alamojuto Ijọba ilu na. Ko si iṣẹ sise nilu tobẹ gbogbo awọn ọmọ ti nwọn si iṣẹ ṣọja jagunjagun ni awọn Oyinbo ko lọ si ilu okere bi Algeria ati Indo - China lati lọ ba wọn jagun.

Nigbati nwọn pada de ile, ko si iṣẹ ti nwọn le fi wọn si, be awọn jagun jagun yi pọ bi iyẹpẹ oju okun. Alairi ibikan fi awọn ṣoja nwọnyi si wa di egungun si awọn alamojuto Ijọba ilu Togo na, o si ba wọn lọrun.

## Ore Ododo

Nwọn ni tẹlẹtẹlẹ nigbati ilu Togo wa ni ọwọ awọn Oyinbo Faranse ti nwọn ko ti bọ loko ẹru, kiṣe Dokita Olympio nikan lo nja fun ajabọ ilu na, on na tun ni awọn enia kan lẹhin; awọn bi ọmọ ilu Ghana ti nwọn npe orukọ wọn ni GARDNER ati CHAPMAN.

Mo gbọ wipe nigbana ọrẹ atata ni Dokita Olympio pẹlu Dokita Nkrumah paapa. Mo gbọ wipe Dokita Nkrumah yi wa ninu awọn ti o nti Olympio lẹhin lati le ja ija a-ja-bọ fun ilu re lọdọ awọn Faranse.

Gbogbo igbayi o ni nkan ti Nkrumah alara paapa nle pa, iyẹn ni bi ilu Togo yio ṣe dapọ mọ ilu Ghana ti awọn yio fi tobi si. O ni bi awọn ko ba le to ilu NIGERIA awọn yio to idaji rẹ, ṣugbọn rigbati ọdẹ pa ẹran tan ko fi lọ ẹnikeji rẹ. Eyi wa di ọrọ ikunsinu fun Dokita Nkrumah pẹlu Olympio alakoso ilu Togo yi.

## Ile Ni ku Wa

Nwọn fi ọrọ na l'ogun l'ogbọn, olukuluku awọn alakoso ilu mejeji wa beresi so'ko ọrọ ranṣẹ si ara wọn. Eyi wa mu Dokita Olympio ki o mọ wipe on lọta kan ni ẹkule on. O wa ba awọn Ijọba Faranse ṣe adehun pe bi Ojo ko ba le ja, ki o ni abu-

(Wo yoku l'oju ewe kẹfa)



## Aworan Dokita Alanu

Dokita Oyinbo alanu ti orukọ rẹ nje Neil Duncan ti o ni ọkọ ofurufu ni on yio ma fi se iṣẹ anu kakiri agbegbe Sokoto ni Oke Ọya nibiti awọn eura ko ti ni anfaani lati ni ile-iwosan ni ẹ nwo aworan rẹ ni apa ọtun awọn mẹta ti o duro ninu aworan na, ti too pẹlu awọn olufanlọwọ rẹ meji, Omidan Leslie Pollard ati Garth Slater, ti nwọn fi aake kọri lati ba a wa lati ilu Oyinbo lati wa ran lọwọ nwo awọn ti o nroko nibiti nwọn yio ti ma fi ọkọ ofurufu rẹ gunlẹ ninu pupa kan ni igberiko Sokoto.

Awọn alakoso Ijọba Nigeria ni bi ọna ti dokita alanu yi fẹ ninu iṣẹ iwosan tirẹ gba ba bọ si, a jọ wipe awọn paapa yio wo o se laipẹ yi.

# ELEI - OFE

ANIUWON KO SE WI LEJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
38, Kosoko Street, Lagos. "ELETI—OFE" LAGOS
P. O. Box 408 Phone 23370

VOL XIV No. 857 SATURDAY FEB: 9, - FEB. 15 1963


# Ala kurumo

Nwọn ni bi ọmọde ba de ibi-ẹru, ẹru aba a ; a ya Oniwe irohin Eleti Ọfẹ kan sara si Ọgbeni Fani Kayọde tise igbakeji Olotu Ijọba tuntun ni Ipinlẹ Iwọ-Orun nisisiyi fun aba kan ti o da lori bi a ṣe le mu IJỌBA GBOGBOGBO (National Government) wa si inu Ijọba ti a nṣe ni Nigeria, yala o jẹ Ijọba apapọse (Regional or Federal) nigbati o mba awọn akẹkọ sọrọ ninu ile-iwe giga ti University College ni Ibadan laipẹ yi. Oni on da a laba ki a dan Ijọba gbogbogboo na wo fun ọdun mẹdogun gbako.

# A—Ba Ti Ko Yege

Ọgbeni Fani - Kayọde tun ṣe alaye kikun lori a-ba rẹ na wipe o yẹ ki awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu ti o ba fi ibo didi pupọ wọle ki nwọn pe awọn diẹ diẹ ninu awọn ti ko ba jẹ alatako ninu ile igbimọ lati wa ba wọn ṣe alamojuto iṣẹ Ijọba fun ọdun mẹdogun gbako.

Nitotọ ko si ẹniti ko mọ wipe ti a ba jọ rin pọ nṣe ni o ma nṣe ni ṣugbọn bi ti ode ọjọ oni kọ. Olukuluku ni o nwa ọna a - pa - s'apo tirẹ fun ara rẹ nipa a nṣelu. JẸ-LỌ ni iwa awọn oṣelu wa da lode isisiyi.

## Ko Lo

Ki a ma purọ tan ara wa jẹ, ko si ọkọ iyawo kan ti o le ra paṣan fun aya rẹ wipe ki o ma fi na on wo fun ọdun marun ambọtori ki awọn ara ilu kan gbe aṣẹ le awọn ẹlẹgiri kan lọwọ wipe ki nwọn ma fi gba awọn bi ẹni gba bọlu lọdan fun ọdun mẹdogun gbako. O ti awọn ara Modakẹkẹ nwọn ko jẹ fun awọn ọmọ Ile Ifẹ ni aṣẹ wipe ki nwọn lo awọn mọ'gba larin ọdun kan gbako bẹni ọkanna ni wọn, ọrọ isakọle lode ni orin d'owe.

Ka tilẹ wa ti ibi iṣana kiyesi ẹtu, awọn ti a le gbe agbara tabi eku-ida Ijọba le lọwọ fun ọdun gbọọran, nwọn ni lati jẹ awọn ti ori wọn f'epo ti oju wọn ti ri kila--kilo, ti nwọn ko nṣe alagbara--mọ--mero ti nwọn yio mọ bi Ijọba ibilẹ lulẹ lainidi.

Ijọba Gbogbo gboo (National Govt) dara nitotọ ṣugbọn awọn nkan elo rẹ nkọ ?

Ọgbeni Fani-Kayọde, ala Kuruma ni aba yin yi ko gbeṣẹ rara.

# Iwe Si Olotu

## Oju Mi Lo Se....

Olotu, Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye lati ba awọn ara wa oṣelu sọrọ diẹ ninu iwe yin nipa iwa ti ọpọlọpọ wa ma nhun ti ọwọ wa ba ti tẹ ẹeku-ida. Awọn Yoruba nitotọ ni nwọn ni ko si ẹniti ao gbe gun ori ẹṣin ti ko ni ṣe ipakọ luke.

Bi o ba di ọjọ oni ti Ọgbẹni Fani-Xayọde, minisita Alamojuto Igbimọ ibilẹ Ipinlẹ Iwọ orun ba ni irọ ni wọn pa mọ on ileri ti on le lọjọ ti on lọ bẹ awọn Igbimọ Ibilẹ wo ni Agege ti o ni ni ọgan ni on le fi gege (tabi nkan ikọwe on tu gbogbo awọn aṣoju igbimọ na ka bi nwọn ko ba mọ iwa hu si on tabi ....

Họwu ! ọrọ wo ni nwọn fa ni ipade awọn igbimọ na ti o to iru ileri bayi ?

Olotu Emi ti mo nkọ iwe yi le fọwọ sọya fun nyin wipe gbogbo ipade ẹyẹ ti nwọn ṣe fun Ọgbẹni Fani-Kayọde ati ọrọ ileri ti on na sọ niwaju wọn wipe on le se ko si nkan ti o sẹhin mi nibẹ. gbogbo rẹ oju mi lo loṣe.

Kilo wa fa sisẹ ninu ọrọ na? Alaito odo wẹ ni a nwipe ki kọnkọ diju ki olodo paapa diju.

Olotu, mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
Yesufu Ojumiloṣe
Agege

## Awe Fun Ese

Mo ṣebi Ọmọ Imale tabi Musulumi Ọgbẹni ni Tajudina Eweina pe ara rẹ tabi a-dara-bi - imale ni, ki o to'sọ wipe on ko mọ nkan ti a ngb'awẹ si.

Ninu oṣu Lamu-lana, ti gbogbo Musulumi mo ni oṣu yọ-ẹsẹ yọ-ẹsẹ, gbogbo awa Imale mọ wipe ninu oṣu na ni Anabi Muhamadu (ikẹ ati ọla ki o ma ba a) palaṣẹ fun wa lati gba'wẹ fun idarijin ẹṣẹ wa.

Nwọn ni ọkan ẹni ni alufa ẹni, ko digba ti a ba fajuro ti a nlọgun kakiri ki Ọlọrun to mọ wipe a ni awẹ.

Fun idarijin ẹṣẹ wa ni a ngba awẹ fun o, Ọgbẹni Eweina.

Emi ni,
Eko Arọwurakewu

## Eleyi Ko Dara !

A dupẹ lọwọ nyin fun ọrọ iwe awọn enia ti nwọn ti ka ti ẹ tun bawa tẹnu mọ wipe ki nwọn gbe iweiyọri rẹ sita gbangba ki a le mọ iye ti gbogbo wa, Hausa, Ibo ati Yoruba jẹ ni Nigeria.

Ọrọ yin ti ja gbangba, a gbọ irohin nipa ipade bonkẹlẹ kan ti awọn Olotu Ijọba wa ṣe laipẹ yi l'Eko pe nwọn ti tun bu mọ awọn enia ti nwọn ri ka nilu Hausa.

Nwọn ni 30 million ni awọn ri ka ni enia nilu Hausa. Olotu eyi ka mọmọ.-o!

A si nwo awọn ọmọ ẹgbẹ alakukọ nkan ti nwọn fẹ ṣe lori ọrọ na, boya nwọn fi ara mọ nitoripe awọn lọrẹ awọn ọmọ ẹgbẹ alaake (NPC) ti nwọn jọ nṣe ilu lọwọ lọwọ nisisiyi. Ki nwọn jọwọ ki nwọn maṣe gbe wa ta o.

Agbokojo, Ibadan
Emi ni K. Bamiwo

## Kanpeni Leyi Tabi Kinni.... ?

O ya mi lẹnu pupọ lati gbọ wipe gbogbo ọrọ ti Ọgbẹni wa Lọya R.A. Fani-Kayọde ti nwọn ṣẹṣẹ fi ṣe Minisita alamojuto Ijọba Ibilẹ ti o tun nṣe igbakeji alamojuto Ijọba tuntun Ipinlẹ Iwọ-Orun ko gbogbo ọrọ alufasa ti o sọ nipa awọn ẹgbẹ oṣelu kan jẹ nigbati o mba awọn aṣoju igbimọ ibilẹ Agege sọrọ ninu ọsẹ ti o kọja.

Ẹ jọwọ, Olotu, ẹ ba wa bere lọwọ Ọgbẹni Lọya Kayọde bi gbogbo akoko ti o nka kiri igberiko Ipinlẹ Iwọu Orun yi "Kanpeni" (Campaign) tabi ipolowo idibo ni o fẹ ma fi i ṣe ni tabi ki o ma gba awọn ara ilu ni iyanju bi nwọn ti ṣe le ma ṣe nile igbimọ wọn ti alafia le ba gbogbo ara ilu.

Akoko ti on na wa lori aga yi ni ao fi mọ bi o ba jẹ ọmọluwabi, ko nṣe wipe ki o ma lo asiko rẹ na fun ebu ara awọn Oselu miran.

Ko si ẹniti ao gbe g'ẹṣin ti ko ni sọ ipakọ sẹhin.

Ipaja Agege.
Emi ni, Ọmọmẹj

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Alaga-Odan

Ki nto bẹrẹ iregbe mi ni ṣiṣe lọsẹ yi o yẹ ki nki ọrẹ mi Ọgbeni I.S. Adewale ti nwọn tun ṣẹṣẹ yan ni Alaga-Ọdan fun awọn ẹgbẹ ti o ma nfi ẹṣin sare l'Eko (Lagos Race Club). Boya ẹnyin ọkawe mi le ma mọ Lọya Adewale ni orukọ ti mo pe yi. on ni ẹ ma npe ni "The Boy Is Good", ọmọ Iya Idita.

Emi Ayiluka alara paapa ti ba wọn f'owo ṣere ]ọdan ti pẹ, nigbati awọn kan ti nwọn wa owo ojiji ti TẸ PALI owo ni mo ti de ibẹ gbẹhin nitorina nko le sọ pato nkan ti nwọn nṣe nibẹ nisisiyi.

Nigbati mo nwi yi mo mọ awọn Oyinbo bi

## LATI OWO AYILUKA

Ọgbẹni Hunter, Vander-Houk ati awọn Kọra bi Mina-ise, Chargoury, Younes, Rossek, Aourd, Aboud ati awọn bẹẹbẹ. Awọn ẹṣin ti o wa lode nigbana ni ROYAL MAIL ati JUBILEE. Bi mo ba ba wọn ṣere ẹṣin ọdan tan l'Eko ma gba Zaria lọ pẹlu Kano mo ba wọn ṣe ere ẹsin ti ilu Jos paapa.

## Jesu Oyingbo

Ọrẹ mi Jesu Oyinbo tun gbe are miran tirẹ de o! O ti tun tẹ iwe kan jade lati ma wa awọn ọmọlẹhin kiri. O ni akoko ku si dẹdẹ. O ni ẹniti o ba fẹ ri Ijọba ọrun ki o ta ile, ki o ta ọna rẹ (gbogbo nkan ti oluwarẹ na ba ni) ki o ma bọwa sọdọ on J. Emmanuel, o si fi ọrọ inu Bibeli gbe ọrọ rẹ na lẹsẹ.

Ọmọ Ijẹbu-Ode ni Jesu Oyingbo, o ti gbagbe pe ọbọ kan ko si ni Idere mọ, eyiti o ku ni Idere ẹwuẹtu ni o wọ gẹgẹbi Jesu Oyingbo alara paapa ti wọ agbada alagbayun ninu fọto ti o fi sinu iwe ti o tẹ jade na.

## TOSB

Mo ki ọrẹ mi Ọgbẹni Owolabi Benson (TOS) Minisita wa ku abọ Liberia ilu awọn ana rẹ tuntun ti o lọ; ṣugbọn nkankan ni ko ye emi Ayiluka si, bi idana iyawo tuntun na lo gbe lọ ni tabi o lọ mọ awọn IN LAW silẹ ni.

Ti o ba jẹ wipe mo mọ igbati o nlọ si ilu awọn ṢIRIMU na ni mba fun un ni aṣọ-adirẹ ilu Abẹokuta ti o jinna daradara ki o fun awọn ana rẹ na nitoripe nwọn ko fi aṣọ-adirẹ Abẹokuta ṣere rara nibẹ. Ko ni wipe a ṣẹṣẹ nfi owo gọbọyi polowo bi ilu Nigeria tiri lọhun, aṣọ-adirẹ awọn Ẹgba ti ṣe eleyi lọjọ ti o ti pẹ ọdọ awọn ara ilu Liberia. Sirimu yẹn do!

## Kurumo Olododo

Ọrọ awọn lebira ti nwọn da iṣẹ silẹ ni ebute ọkọ elefin ni Apapa, Eko, Sapẹlẹ ati Warri jẹki nniran awọn aladugbo wa ti a npe ni Kurumọ ni aiye atijọ ti nwọn ti mba wa ṣe iṣẹ a-nko-ẹru sọkọ lebute ri ki Ọgbẹni W. H. Biney to fi iṣẹ ti o nṣe labẹ awọn Oyinbo oniṣowo ti a npe ni Miller Brothers silẹ l'Ẹhingbẹti lati lọ ko awọn ara Ologbondoko, Ganma, Dọfinan,, Illa, Ijagbo, Ọbaloyan, Alakukọ mọ awọn ara Oke-Ọdẹ wa s'Eko wa gba'ṣẹ na mọ awọn Kurumọ lọwọ.

## Owo Lebira

Awọn Kurumọ lagbara pupọ, ẹhin ọrun wọn ni nwọn ma nfi ru apo koko (cocoa), ekuro ati apo ẹpa. Nwọn ki yọnu pupọ nipa owo iṣẹ won, ṣugbọn o ko gbọdọ fi iresi pẹlu ẹran oniyọ du wọn rara. Aiye ti lu ja ara wọn nisisiyi, awọn lebira nfẹ silemejila ati abọ lojumọ. Nigbawo ni idamu ko ni po larin ilu? Ijọba ki rọ owo, mo fẹ ki awọn lebira yi mọ wipe awọn iyawo wọn ti nwọn fi silẹ nile ni nwọn yio fi owo iyọ ati owo iṣana san owo ti nwọn fẹ gba yi.

## Okan Lesin

Iwe wosika kan ti emi Ayiluka ri gba lati ọdọ Ọgbẹni Imale kan lọsẹ yi niyi nipa iyan ti awọn ẹlẹsin kan mọ njiyan wipe Anabi kan ni ni ọna ẹsin rẹ tọna ju. Emi ko ṣe igbagbọ nko ẹe Imale ṣugbọn mo mọ wipe ọkan mi aluf'a mi. Ẹ ka iwe Ọgbẹni Lamidi na:

"Mo ro wipe niarin igboro Eko yi ko si ẹniti yio sọ wipe on ko ti gbọ nipa awọn kan ti nwọn ma mba ara wọn jiyan nipa anṣe alaye Alkurani ati Bibeli, wipe ọkan lo tọna tabi ekeji ni. Awọn ti nwọn ṣina nṣe arivaanjiyan na ni awọn bi Apostle Adetoro, Alhaji Akewukewe, Alfa Hosẹan, ati Ọgbẹni Awoṣika.

"Nigba miran ti nwọn ba si nṣe anyanjiyan o pẹ ma fa ibinu larin wọn, nkan ti o si ma Ọlọrun kan, apẹrẹ ni eleyi nigbamiran ti Apostle Adetoro ba so nigbamiran wipe Anobi Mohammed ki ṣe Ojiṣe Ọlorun ati pe iwe Mimọ Kurani ki ṣe iwe ti o tọna rara, eleyi si ma nfẹ fa ijangbọn nigbamiran".

# Oko Ofurufu Tuntun



**Aworan yi ni ti oko aropileni tuntun ti awon Oyinbo Gesi sese gbe jade laipeyi ti nwon si lo danwo ninu afefe fun adota wakati laisi iyonu kan rara**

# Itan Ọba Alake Ademola Keji

## (Lati Owo Omo Abati)
## Ago-Owu Abeokuta

Lati igbati Ọba Alaiyeluwa Ladapọ Ademola Keji ti waja ni iwọn nkan bi oṣu meji sẹhin ni gbogbo awọn ọmọ ọba ti Oye ọba to si lati jẹ ti nfi iwe wọn ṣowọ si awọn afọbajẹ pe idile awọn ni Oye Ọba na kan.

N gbati Ọba Gbadebọ Alake waja oju ko la to bayi, gbogbo awọn ti o ndu oye Ọba nigbana bonkẹlẹ ni nwọn nse e. Ẹnikẹni ti o ba tilẹ jẹ ọmọ ọba ni lati jinna si Afin ni aiye atijọ: ninu ki nwọn da Ifa ki o muu ki nwọn si lọ muu ni ojiji nibiti o gbe nṣe iṣe. Ọrọ ti kurc bẹ nisisiyi.

### Ademola J'oba

Gẹgẹbi mo ti sọ ninu iwe itan mi pe ọdun keji ti ogun Adubi pari ni Ọba Gbadebọ, Alakẹ ana, waja ti awọn Ẹgba Ologboni si bẹrẹsi ro ẹniti awọn yio gbe oye Ọba Alake na fun Awọn kan ni Ologbe Pa J.K. Coker, ọmọ Ajọbọ ni Iporo Ake ni awọn fẹ ki o jẹ oye Ọba Alake na nitori wahala ti o ṣe nigba ogun Ijẹmọ ati ti Adubi. Pa Coker funrarẹ ni o tọka Ọmọ-Ọba Ladapọ Ademola fun awọn Ologboni Afọbaje wipe on ni oye na tọsi atipe ọmowe ni on si ro wipe yio mu ilọsiwaju wa si ilu Abẹokuta ija ko ni si mọ, ọtẹ ko si ni si mọ.

Awọn Ologboni afọbaje na si gba si lẹnu, nwọn fi ohun wọn ṣọkan lati fi ọmọ Ọba Ladapọ jẹ Ọba Alake na, Nwọn mu lọ si si Ipebi ninu osu keje (July) ọdun 1920 Iyen di ọdun mejilelogoji nisisiyi.

Lẹhin ti ọba yi ti ṣe oṣu meji abọ ninu ile Ipebi na tan ni nwọn ba ṣe ẹye igbade-lelori fun un

Ẹyẹ igbade lori na ka momọ gbogbo ẹsẹ awọn ọmọ ẹgbẹ ti o wa ni idalẹ ni o pe ṣibaṣiba si ibi aṣeyẹ na. Gomina-agba Sir Hugh Cliford, ti o wa l'Eko nigbana wa ati Bisọbu Oluwọle pẹlu awọn enia jankan jankan. Emi paapa ti mo nkọ iwe yi, oju mi ni gbogbo rẹ ṣe.

Bi awọn onilu ti nlulu, ti gbogbo enia si njo ni nwọn nkọrin bayi:

Ademola jọba ilu toro ni i,
Ijaiye ko binu,
Ẹgba ko mọ binu,
Ademọla jọba ilu toro nini.

Gbara ti Ọba yi ti gun ori oye ni o paṣe wipe ki nwọn da awọn Oloye Ogboni mẹta ti nwọn ti mọle lori ọrọ Ogun Adubi silẹ. Awọn Oloye na ni Ṣọgade, Agbakin Ikija, Lunloye Balogun Itori ati Laoṣebikan, ẹniti iṣẹ ibatan Alake alara paapa.

Gẹgẹbi ati mọ wipe onigbagbọ ni Ọba tuntun yi, nigbati o ti gun ori oye tan ni o ba mura lati lọ ṣe isin-idupẹ ninu gbogbo Ṣọṣi ti o jẹ pataki pataki ti o wa ni igboro ilu Abẹokuta.

### Kuti Olorin

Awọn ọmọ Ẹgba jẹ iran kan ti nwọn fẹran orin kikọ papọ. O tilẹ fẹ jẹ wipe idaji orin inu iwe Ṣọṣi ti awọn onigbagbọ ma nkọ ninu iwe, awọn Ẹgba lo kọ eyiti o pọju nibẹ. Gẹrẹ ti Ọba Alake Keji yi ti gun ori oye tan ni alufa agba J. J. Ransome Kuti (baba Ologbe "Dawodu") ti Ṣọṣi Ake ti bẹrẹsi ronu orin ibilẹ Ẹgba ti o ba oju mu ti a o ma kọ fun Ọba tuntun na.

Eyi si ni ọkan ninu orin ibilẹ meji ti Alufa Kuti fun awa Ẹgba fun Ọba Alake ni 1920. Orin na si ba oju mu titi di ọjọ oni. Mo tẹ ọrọ orin na fun anfani awọn ọkawe mi, awọn ọmọ Ẹgba ti ko mọ gbogbo ọrọ rẹ ri.

(I) Ẹgba alake ẹ ṣe giri
Ẹgba Oke Ọna ẹ fi mọ ṣọkan
K'abẹ Olodumare k'o d'Ọba si.
K'abẹ Olodumare k'Ọba ko pẹ.

(2) Ẹgba Agura ẹ mura ni, Ẹgba Olowu ẹ giri ẹdọ,
Ẹjẹ kajọ wo'lẹ f'Ọlorun wa.
Kọlọrun d'Ọba Alake si.

(3) Ọba Alake kẹ gbo, k ẹ tọ, Kade pẹ lori ki bata,pẹ lẹsẹ.
K Ọlọrun Setẹ ọta fun nyin.
K Olodumare S'apata yin.

4 Ẹnyin ọmọ Ẹgba ẹ tẹ wọ yin.
Ẹnyin ọmọ Olumọ Abẹluku,
Kabẹ Olodumare ko da wa si.
Kaiye ko tutu kari bigbe.

(Iyoku di ọsẹ ti mbọ)

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kavachas, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.
[illegible] by Air Mail for Catalogues and Literature.
HINDU SANKARA, 10 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England




## Bawo Ni Olympio Se Ku?

( O bẹrẹ loju ewe kẹta

ro ti e gboju nile.

Ilu Faranse pẹlu Togo wa fi ọwọ bọwe adehun pe ki awọn jọ dawọ na ẹnikẹni ti o ba fẹ ba awọn mejeji ja. Awọn ti ko mọ nkankan ni Olympio tun fẹ ta awọn fun Ijọba Faranse ni, nwọn ko mọ wipe ọrọ na nidi.

### Awọn Asalu

Ijọba Faranse nikan kọ ni alakoso ilu Togo yi mba sọrọ, o tarainọ Ijọba Gẹsi ati Amerika paapa. Eyiti ọrọ awọn alasalu (refugees) paapa da silẹ ni ṣ pẹ ninu iku Olympio nitoripe nigbati nkan bẹrẹsile fun awọn oṣelu alatako ilu Ghana ọgunlọgọ wọn ni nwọn sa asala lọ si ilu Togo; eleyi ko si dun mọ Nkrumah ninu tobẹgẹ ti o fi nfẹsun sun wipe ijọba Togo nwa iṣubu on.

Nitotọ awọn alasalu (refugees) ti o sa lati Ghana lọ si Togo fun abo ju ẹgbẹdọgbọn (5,000) enia lọ, bẹna si ni awọn alasalu miran tun kuro ni Togo lọ sa si ọdọ Nkurumah ni Ghana. Ninu awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu alatako ti o sa lo fara pamọ lati Togo lọ si Ghana. Antonio Meatchi, ti o fi igbakan ṣe minisita Meatchi, ti o fi igba kan ṣe minisita alamojuto nkan ọgbin labẹ ijọba Ọgbẹni Grunitzky.

Iyoku di ọsẹ ti mbọ).

E ma ka Iwe Irohin Eleti-Ofe
Tio kun fun Irohin Aladun.

# News From All Over Africa

## British Tractors For Ghana Forests

KUMASI (GHANA)- The Bibiani Logging and Lumber Company Ltd., of Kumasi have ordered 10 heavy-duty "Mandator" tractors worth £32,000 from the British firm of A. E.C. Thirteen of these tractors were purchased by the same company in 1961. They will be used for semi-trailer work in the Machegany forests.




Facts speak for themselves. This venerable veteran, a truck type Lo 2000, vintage 1934, has covered 1,367,000 miles. No doubt it would have gone on if Daimler-Benz AG had not bought it back at the ripe old age of twenty-five. Of course not every Mercedes-Benz can have such a long working life. However, all Mercedes-Benz vehicles are built to last just as much now as they were then, to give many years and many miles of trouble-free economical service.

MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (EB), IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT HARCOURT, ABA

SUB-DISTRIBUTORS:

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY, ONITSHA, ABA.


## Nigerian Actors In B.B.C Play

LONDON—British televiewers saw several Nigerian actors playing important roles in a tense drama about a mythical African country, this week.

Written for the B.B.C by Basil ..., the play "Waiting for Wanda", told the story of a great African Leader, risking his life to prevent an armed uprising among his people because, he said, "only by peace can we reach the independence which is coming."

Yemi Ajibade, a young Yoruba who is rapidly building himself a reputation as actor and musicion in films, television and on the British stage, played a leading part (that of Joshua, a house steward).

Now in his early 30's, Ajibade at the International Edinburgh Festifal with leading British actor Robert Morly. But his best known appearance was probably in "The Blacks" by Jean Genet which had a sneeessful run at the Royal Court Theatre in appearing in respertory at Colchester, Essez.

For Joseph Layode, a former chool teacher in Western Nigeria, the production brought the number of his performances on stage and television since he came to Britain to nearly 40. He is now appearing in London in "Born Yesterday", staged by the Actors Workshop.

# Awon Osise Oko Da Ise Sile

(O bere loju ewe kini)

## O de Gongo

Ọrọ wọn na wa de gongo ni owurọ ijẹrin nigbati awọn onișe ebute na ko awọn lebira kan wa si ebute ọkọ l'Ẹhingbẹti pe ki awọn yen ma ba ișẹ ti nwọn kọ silẹ na niso. Awọn lebira ti o ti wa nibi ișẹ na tẹlẹ ni enikan ko g odọ fọwọ kan awọn ẹru na lati ma ko sinu ọkọ.

Bi nwọn ti berẹsi ko awọn ẹru na ti nwọn nfa a mọ ara wọn lọwọ ni awọn Ọlọpa-bi-o--ti-leri-ko-ri ti awọn ọga ișe na pe wa s'ebutọ ba fa kunmọ idi wọn yọ ni nwọn ba bẹrẹ ijakadi lati inu ọgba ebute ti ọkọ ngun si; ija na bẹrẹsi tan titi de Oke Ologbwo.

Nigbati ọlọpa ri wipe ọrọ ija na kọja ti onikumọ, ni nwọn ba fa bọmbu elefin yọ ti nwọn bẹrẹsi jan wọn mọlẹ lati le fi din agbara awọn oșișẹ na ku. Awọn ti o șubu șubu lulẹ, awọn miran si nja lọ bi rẹrẹ. Ọpọlọpọ awọn ọlọpa ni nwọn f'ara pa.

## Lebira Ilorin

Awọn obi ti o ni awọn ọmọ ni ilewe nsare lọ fa awọn ọmọ wọn jade; awọn Oyinbo onisowo l'Ẹhingbẹti paapa sare ti ilẹkun sọbu wọn. Oku ad.e ko mọ ẹniti o kun on ni ọrọ na.

Irohin ti a tun gbọ nipa ọrọ na loru ana ni pe gbogbo awọn igbimọ awọn oșișẹ jake-jado ti faakekọri wipe ti awọn alamojuto Ijọba ko ba pe awọn ọga ibișẹ ebute nwọnyi ki nwọn ro ọrọ owo ișẹ ti ko na șe awọn paapa y i o da i ș ẹ awọn silẹ laipẹ yi nitori ti wọn.

Akọwe irohin wa ti o tẹ waya si wa lati Ilọrin ni awọn ọga alagbașe ișẹ ti nwọn nwa lebira kakiri igberiko Ilọrin bi Dọfian, Oke-Ọddẹ, Omupo, Ganma Illa, Ajașẹ, Ọbalọyan ati bẹbẹ ko ti ri awọn enia ko tobẹ. Awọn gbajumọ inu wọn ti nwọn lọ si ile Ọba Ilọrin, Mallam Sulu Gambari, lati lọ ki i pe boya o le ran wọn lọwọ lati sọ fun awọn enia r ẹ p e ișẹ și ilẹ l'Eko, nwọn ko ba a nitoripe Ọba na ti ba Sardauna Sokoto lọ si ilu Mẹka lati lọ șe "Kunkari" adura pataki loju Orori Anabi fun ọjọ meje gbako.



## Pa Aina Onabolu Jalaisi

EBUTE—MẸTTA—Anu șe wa lati tufọ Oloye Aina Ọnabolu ti o jalaisi ninn ile ti o ngbe ni Ọsholake Street, Ebute—Mẹtta ni alẹ ijeje ọjọ ọsẹ.

Ẹni ọgọrin ọdun ni alagba na nigbati o ku, o si jẹ ẹnikinni ninu awọn enia-dudu ti o kọ fi a nfọwọ ya aworan (fine arts) șe ișẹ șe, ti o si bẹrẹsi kọ gbogbo awọn ọmọ ile ẹkọ ni ișẹ a-nfọwọ ya aworan yi kakiri ile ẹkọ.

Baba yi ni awọn Ijọba gbe ișẹ yiya aworan awọn ile ti nwọn fẹ kọ si Yaba fun gbigbe awọn akọwe fun ni iwọn nkan ọdun mejidinlogoji (1925) sẹhin ki nwọn to ma kọle si gbogbo ilẹ ti Ijọba gba nigbana.

**Asiri Tu Sepo :**

# Tubman Ni Awon Olote Fe Pa On

MONROVIA - (Liberia) - Balẹ ilu Liberia Ọgbẹni William Tubman ni awọn ọtẹlẹmuyẹn ilu on, awọn ti on gbẹkẹle ti tuna așiri awọn ọlọtẹ kan ti nwọn ditẹ lati pa on ki nwọn le gba Ijọba ti on șe alakoso rẹ lọwọ on.

A gbọ wipe awọn ogunna gbongbo alakoso Ijọba ilu na marun ni nwọn ti mu ti mọ ile lori ọrọ na, șugbọn nwọn ko da orukọ wọn sinu iwe waya irohin ti o tẹ wa lọwọ lori rogbodiyan na.

# Oke Leye Nfoun!

**Omoge Omuwe Linda Ludgrove f o s'oke nitoripe o mo we pupo.**

Printed and Published by The Union Printing & Publishing Company 28, Kosọkọ St., Phone 23370 Lagos
Editor (Olotu) Ọla. Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos.